# Awọn iṣẹ :Umura

Yoruba يوربا




5 Fifa irun tabi gigẹ ẹ lọọlẹ

Fifa irun tabi gigẹ ẹ lọọlẹ wa fun ọkunrin nikan, Ṣugbọn obinrin maa ge odiwọn ọmọnika kan kuro ninu irun rẹ

## Awọn eewọ Arami:

1. Mimu irun kuro lori ati ara
2. Gige eekanna
3. Lilo lọfinda
4. Ṣiṣe igbeyawo fun ara rẹ tabi fun ẹlomiran
5. Biba obinrin lajọ ṣepọ
6. Pipa ẹran ori ilẹ lọna didẹ ọdẹ

**Awọn eleyi ti o jẹ eewọ fun awọn ọkunrin nikan:**

1. Wiwọ aṣọ, oun naa ni aṣọ ti wọn ran si ara gẹgẹbi aṣọ-wiwọ tabi ti wọn ran fun orike kan ninu awọn orikerike ara
2. Bibo ori pẹlu nkan ti o lẹ mọ, gege bii lawani ati fila

**Awọn eleyi ti o jẹ eewọ fun awọn obinrin nikan:**

1. Bibo oju pẹlu niqab tabi iboju, ṣugbọn ti obinrin ba wa níwájú àwọn ọkùnrin àjèjì, yio fi ìbòjú rẹ̀ bo ojú rẹ̀
2. Wọ awọn ibọwọ

## Awọn nkan ti wọn fẹ ka ṣe ni Umura:

1. Gige eekanna ati fifa irun ti o jẹ dandan ni ki a fa a ṣiwaju ki a to da aniyan gbigbe arami
2. Wíwẹ̀ fún arami
3. Lilo lọfinda si ara fun awọn ọkunrin ṣiwaju ki a to wọ aṣọ arami
4. Riro aṣọ ìbàdí funfun àti aṣọ idabora funfun fún àwọn ọkùnrin
5. Gbolohun Talbiya ( Labaika Allahuma Labaik. Labaika Laa sharika Laka Labaik. Ina alhamda wa nnimata Laka wal mulk. Laa sharika lak ) lati igba ti a ba ti gbe arami titi di igba Tawaf
6. Pipakaja nibi Tawaf fun awọn ọkunrin – oun nipe ki o ṣi ejika ọtun kalẹ
7. Ifẹnuko okuta dudu
8. Iyara rin nibi ipoyi mẹta akọkọ
9. Yiyan Nọfila rakah meji lẹyin Maqam Ibrahim